# Idahun Evangelist Akande si ọrọ Bọlaji Akewukewe

(Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande, Ogbomọshọ)

KO ya mi lenu rara nigbati mo ri idahun Bọlaji Akewukewe ka ninu "Irohih Yoruba" ti ọjọ 23-11-58. Mo mọ pe okun lo mu Bọla-ji ti o fi bẹrẹ si dun ni idun-kudun, oro otitọ lo taa lara tobẹ ti o fi nfọ ifọkufọ. O sọ ọrọ da silẹ putuputu gẹgẹbi iṣe rẹ, awọn ọrọ na ko lori ko ni idi nitoripe iro, arosọ, ahesọ ati aroye lasan ni gbogbo oro na jasi. Akewukewe npe ara rẹ ni ologbon, o nfẹ ma a se bi ologbon, o nfẹ fi ara rẹ han gegẹ bi eniti o ni imọ, sugbon ko mọ nkankan, gegẹ bi Iwe Jobu ori 11, ẹsẹ 12, ti wi bayi pe, "Enia lasan a sa ma a fẹ iṣe ologbon, bi o tilẹ bi enia bi ọmọ kete-kete." Ejo ti a be lori lo-riji, o gbodọ jowere gidigidi, beni ọrọ Akewukewe ati awọn Imale ẹgbẹ rẹ. Iwasu ẹdẹ lo nta wọn lara.

Ninu awọn ọrọ pataki marun ti mo fi tu asiri ẹsin Imale, sibẹ Akewukewu ko ti i le yanju eyọ kan ninu wọn, aroye lasan lo nfi gba inu Iwe Irohin, Bọlaji npe ara rẹ ni Imale, sibẹ ko le sọ, ko si mọ ẹsẹ tabi aya Alkurani ti o le fi yanju ọrọ ti o nsọ. Bibeli lo nlọ tokasi, beni ko si ohun to kan Bibeli pelu isekuse ẹnyin Imale. Akewukewe a ma a yan Bibeli pupọ nitoripe Bibeli rọrun pupọ fun gbo-gbo enia, o si dun ka, o si kun fun oro otitọ pataki ju Alkurani lo.

Bi Bọlaji ba mọ pe Imale tootọ ni on iṣe, ti o ba si mọ Alkurani dada, mo fẹ ki o fi Alkurani dahun awọn ibere mi meji pere yi—1) Ninu Surat ati aya wo ninu Alkurani ni nwọn ti pa a laṣẹ fun ẹnyin Imale pe ki ẹ lo ma a pon okuta la ni Mekka? Nibo ni Alkurani ti sọ fun nyin pe ki ẹnyin Imale ma a pa agbo ẹran Ileya ti ẹ nṣe lọdọọdun? Mo nfẹ idahun ọrọ wọnyi lati inu Alkurani. Ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" ẹ ma kiyesi i, aroye lasan ni Bọlaji yio tun gbe kalẹ ti yio tun ma a sọ ohun ti ko ye e ninu Bibeli, nitoripe ọpọ-lọpọ ohun ti nwọn nṣe ni ko si ninu Alkurani, sugbọn ọna onjẹ ni nwọn nlepa.



Evangelist J. J. Akande

Iro Akewukewe tun fara-han nipa awọn ọrọ ti o sọ nigbati a pade ni Ogbomoṣọ ni ọdun 1951, gbogbo awọn enia ti o wa sibi ipade na ni o mọ daju pe ni ọjọ keta ti a o pade soro ni Akewuke-we lọ ko sinu Hall ti o bere si gba sile kookan lọwọ gbo-gbo enia, awa onigbagbọ ati apa kan ninu awọn Imale paapa lodi si eto owo ti Akewukewe ṣe na, ki iṣe awọn Imale Ogbomoshọ lo gbe eto kalẹ rara, awọn Imale gbomoshọ ki iṣe oni-ṣekuse tobẹ rara. Nigbati a sọ titi pe ki Akewukewe Bọlaji bọ sode, ṣugbọn ti jagu taku sinu yara, eyi lo fa a ti awọn onilu (drum-mers) Ogbomosho fi nfi Bọlaji lu ilu bayi pe: "Ake-wukewe ti ilekun m'ori ko le jade" gbogbo irohin na ni a si kọ sinu iwe "Irohin Yoru-ba" ti gbogbọ awọn ti o wa lokere rere si ri i ka.

Bi o ba jẹ pe Bọlaji lo bori ninu ipade ọrọ sisọ na, ninu iwe irohin wo ni irohn ọrọ na ti jade? Eṣe ti ko lẹ awọn oro na jade ni akoko na? Bọlaji tun sọ pe awọn ọlọpa ti ọmọ ọdọ mi kan mọle lọjọ na, eṣe ti irọ pipa fi dun 'enu awọn t'o ba npe ara wọn ni Akewukewe bayi? bẹni nwọn ko ke nkankan ju irọ lọ. Lọjọ ti awọn Imale Bọlaji wa sọ mi ni okuta, ọlọpa ti o wa mu enia mẹfa ninu awọn Imale ọjọ na, ti mo si tun gba wọn silẹ gẹgẹbi iwa awa Onigbagbọ, ọlọpa na mbẹ ni ilu Oshogbo lọjọ oni yi, iwe ti awọn ọlọpa si kọ ọro na si, o wa ni Office awọn ọlọpa Ogbomoshọ titi di oni yi, bi e ba puro tị Mẹkka fun wa ti a ko si gba, e tun fẹ ma puro ti ilẹ wa nibi fun wa? Bi o ba re o nina ida-hun, jẹki ẹlomiran gba ipo rẹ.

Akewukewe sọ pe gbogbo ẹran ọlọra ni nwọn npe ni **Budna** ni ede Larubawa, ẹnyin Imale toku si dakẹ? ko tilẹ kuku si ọlọgbọn kan-kan ninu nyin ni, ti Bọlaji fi npurọ fun nyin ti ẹ si gba? Njẹ mo bere lọwọ Bọlaji, malu ti o ba lọra, ati ewurẹ ati agbo ti o ba lọra, **Budna** na ni gbogbo wọn njẹ ni ede Larubawa? Tọkasi ibiti ọrọ na ba wa ninu Alkurani, emi yio si fi han ọ ninu Alkurani pe ọtọ ni orukọ Rakunmi, ati ti malu, ati ti ewurẹ. Bọlaji ko mọ nkankan rara, agidi ni o nlọ, gẹgẹ bi ọrọ Owe 9: 13, ti wi bayi pe "Alaroye ati ope ni, ko si mọ nkan". Ati gẹgẹ bi Timoteu keji ori 3, ẹsẹ 9, ti wi bayi pe, "Sugbon nwọn ki yio lo si-waju ju bẹ lo, nitori were

*Wo oju ewe kẹsan*





O ṢE IWOSAN AWỌ-ARA O NPA IRORA . O NLE OTUTU LỌ



Mentholatum je ipara iyanu ti nwo'nia san pelu itura, bi isaka ba nyọ e l'enu pupọ, bi o ni efori tabi irora, bi o ba ni aisan tabi otutu egbonrirì, Mentholatum ni ki o wa. Ororun o si yara aise. Sa fi pa'ra. Ni laeju-aya ni wa a ti gbadun

ṢA A MA A FI PA A

IPARA TI O DARA JULỌ

Bi o ba tiṣe tete lo Mentholatum si ni yio fi tete fun O ni igbadun si.
Fi pa ibiti o ndun ọ. Irora na yio si lo lesekanna.
Fi pa igbaaiya daradara ki o si fi die bọ imu. Otutu na yio silọ.
Fi pa gbogbo ara rẹ, ara rẹ yio si gbadun
Mentholatum nṣiṣe kiakia ni, ko si nkan ti o f'ara jọ o. Ra igo rẹ tabi agolo rẹ kan l'oni.
Bere fun ojulowo MEN-THO-LAY-TUM.



MENTHOLATUM

*Awọn enikanṣo na ti o nṣe e ni The Mentholatum Co. Ltd. (Est. 1889) Slough, England.*

# Ọdun ọdunni o yabo! Ọdun ọdunni o yabo!!



Ẹ ba a t'ẹnu b'epe k'ẹ tẹ'nu bọre, ọdun ọdunni o yabo !!!

# Idahun si ibere S. B. Ọjẹniyi

**E JOWỌ gba mi laye lati dahun si ibere Ọgbẹni S. B. Ojẹniyi (carepnter) Ijomu, Otun-Oro ti o jade ni oju ewe keji Iwe "Irohin Yoruba" ti ojo Aje ti ise ojo kẹdọgbọn osu kejọ odun yi pe ẹko akoju a ma a sọ enia di were na?**

Idahun t'emi si ibere yi ni wipe, ẹkọ akoju ko sọ enia di were, lotitọ gbogbo nkan ni o dara ni iwọntun-iwọnsi. Orisirisi ni were, ọtọ ni asinwin, ọtọ ni dindinrin bẹna si ni were. Bi ko ba ni ọwọ aiye ninu, ẹkọ akoju ko le so enia di were sugbọn o ma a nso enia di akindindiorin nitoripe igbakugba ti o ba ri awọn ti nkọ iru ẹkọ bayi nṣe ni nwọn yio ma a jẹnu wuyẹ-wuyẹ—bi i ki a ma a da nikan sọrọ.

Ti nwọn ko ba tete da a duro fun igba diẹ, o le ti ipa bayi di Akindindinrin ti yio fi jẹ pe bi o ba sun kanhun-kanhun ni yio ma a sọ lẹnu bi agogo Soosi nipa siso Giriki mọ Latini sugbọn ti o ba ni ọwọ aiye ninu ko ni i ti to bayi ki o to di were pelu iwọnba ti o mọ na, elomiran ndi were laijẹ pe o mọ iwe rara. Lakotan, ẹkọ akoju ki i sọ enia di were, Akindindinrin ni nsọ enia da.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
JOSY OMỌ-AKINDELE.
Post and Telegraphs Department, Gbọngan.

Awọn meji ti idahun wọn dọgba pelu ti oke yi ni'—

1. S. Ọla. Buraimo 2, Odubiyi Street, Itirẹ Road, Mushin
2. Israel Bode Ọke, Iye-Ekiti.

2

Idahun temi si ibere yi ni pe, ẹkọ akoju a ma a sọ enia di were. E ṣe akiyesi iru awọn ẹni bẹ ẹ . inu igbo ni nwọn nfẹ ma a lo gbe, nwọn a ni kosi ariwo nibe, nwọn ko fẹran lati ma a duro ti ọpọ enia. Fun apẹrẹ were kan wa ni Bẹrẹ nwon npe e ni Akin's Akọ, ẹko akoju ni o da a lori ru, ti o ba nso ede Oyinbo awon oniwe miran ki i mọ itumọ re ni.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
ỌLAMILOKUN AMỌLE.
Ile Odẹkunle,
E5/275 Isalc Oje,
Ibadan.

## Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu Amuye ṣe ikore ọdun

AMUYE.

NI deede agogo mẹwa arọ ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu kọkanla odun ti o koja yi ni Ẹgbẹ Mimọ Kerubu ati Serafu Amuy ṣe Isin Idupẹ Ikore Ajọdun wọn, Prophet J. A. Fadeyi si ni Alaga ọjọ na. Ọgbẹni John Iyiọla ni o ka ẹko kini lati inu Dept. 26: 1-11, Ọgbẹni J. Araromi si ka ẹko keji ninu Matteu 13: 24-51, lẹhin eyi ni Prophet D. A. Ajide ṣe iwasu, o si yan ẹsẹ koko ọro iwasu re lati inu Jobu 14: 5 ati Oniwasu 1: 9, o si ṣe opolopo ọjọ na ni Phillip Dele.

Lẹhin eyi ni Ẹgbẹ awọn Akorin ti o dẹ si ilu yi lati Isanlu-Isin korin aladun, Ikore na dun pupọ, irohin ko to afojuba ni. Die ti aye wa fun lati daruko ninu awọn enia pataki pataki ti o wa sibi Idupẹ ikore na ni awọn Ọgbẹni M. O. Fadeji, Aṣiwaju Ẹgbẹ Bimọ Kerubu ati Serafu Ilu Isanlu Isin Joseph, Alape, J. A. Ọlaoye, Daniel Adedipẹ, Peter Fadipẹ E. Ajibade, Onilu ojo na ni Phillip Die.







# Evangelist Akande

*Lati oju ewe kẹrin*

wọn yio farahan fun gbogbo enia gẹgẹ bi ti wọn ti yori si". Gbogbo nyin ni yio ri i gẹgẹ bi Bolaji yio ti ma kosẹ losan gangan nigbati ko ba mọ ohun ti yio sọ mọ.

Bolaji so pe itukutu ni Bibeli ede Yoruba, ati pe aṣiṣe kun inu rẹ. Otitọ ni ko ye Bolaji ti o fi wi be, ninu gbogbo ẹsẹ Bibeli ti Bolaji tokasi gẹgẹ bi itukutu, ko si eyiti o kọ enia ni ẹkọ buburu gẹgẹ bi Alkurani ti ko enia ni ẹkọ buburu. Bi ẹ ba ri aṣiṣe ninu Bibeli, awọn ti nwọn nto ọrọ na ti nwọn si nte ẹ le ṣe aṣiṣe, ṣugbọn ki iṣe aṣiṣe tabi aṣiso ti o le mu enia ṣina, ki iṣe eyiti o le sọ enia di ọta Ọlọrun ati ọta enia gẹgẹ bi ti Alkurani. Awa Onigbagbo tile dupẹ lowo Ọlọrun fun imọ ti a ni, ti a fi tumọ Bibeli lati ede Heberu si ọpolọpọ ede gẹgẹ bi Greek, Latin, Oyinbo, Yoruba, Hausa, Ibo, Tapa ati bẹ bẹ lọ. Ṣugbọn lati odun ti Alkurani ti wa ni ede Larubawa, ninu ede kanna lo wa titi di oni yi, bi ẹnyin Imale ti pọ to laiye yi, ẹ kan pọ lasan ni, ẹ ko ni ọgbọn ati imọ ti ẹ fi le tumọ Alkurani si orisirisi ede miran, ti ọpọ enia fi le ma ri i ka dada gẹgẹ bi gbogbo enia ti nka Bibeli lode oni.

Ọpolọpọ ẹkọ buburu ati ọrọ isokuso buruku lo kun inu Alkurani, ti awọn Imale paapa ri i, ṣugbọn ti ko han si ẹniti ko ba mọ kewu, bakanna ni aṣẹ ati ẹkọ buburu ti Momodu fi kọ awọn Imale kun inu Alkurani, iwọnyi ko han si gbogbo enia, awọn Imale ki isi fẹ ki enia mọ rara, ṣugbọn diẹ ninu iru awọn ọrọ ati ẹkọ bubuu bẹ ni wọn iba ti aye le gba niwọnyi ti emi yio fihan nyin—

1. Ninu Alkurani Surat 5, aya 51, o sọ bayi pe, "Ẹnyin ti ẹ gbagbọ (Imale) ẹ maṣe mu awọn Juu ati Kristiani ni ọrẹ nyin. Ọrẹ ara wọn ni nwọn nṣe, bi ẹnikẹni ninu nyi ba si mu wọ l'ore, dajudaju ẹni na di ọkan ninu wọn........" Ninu ọrọ Alkurani yi, Momodu sọ fun awọn Imale pe nwọn ko gbọdọ ba awa Onigbagbo ṣe ọrẹ rara, njẹ iru ẹkọ yi dara? Njẹ ọta lo ha yẹ ki a ma ba ara wa ṣe? Ẹkọ buburu ni eyiti Momodu kọ nyin yi. Ṣugbọn Jesu Kristi kọ awa ọmọ-ẹhin Rẹ ni ẹkọ rere ninu Matt. 5: 44-45. bayi pe, "Ṣugbọn Emi wi fun nyin, Ẹ fẹ awọn ọta nyin, ẹ sure fun awọn ẹniti o nfi nyi re, ẹ ṣore fun awọn ti o korira nyin, ki ẹ si gbadura fun awọn ti nfi ẹrankan ba nyi lo. Ki ẹnyin ki o le ma jẹ ọmọ Baba nyin ti mbẹ li ọrun, nitoriti o ngmu ọrun Rẹ ran sara enia buburu ati si ara enia rere,O si nrọ ojo fun awọn olotọ ati fun awọn alaiṣotọ." Dajudaju, ẹkọ ti Jesu kọ wa lati ma fẹran gbogbo awọn ọrẹ ati awọn ọta wa yi, o jẹ ẹkọ rere fun gbogbo enia, ti inu Ọlọrun ati enia si dun si.

2. Ninu Surat 47, aya 4, Momodu sọ fun awọn Imale bayi pe, "Nigbati ẹnyin ba pade awọn alaigbagbọ, ẹ ma a ke ori wọn kuro l'ọrun wọn titi ẹnyin yio fi ṣẹgun wọn, ki ẹ si fi awọn toku sinu ẹwọn, lẹhinna ki ẹ jẹki nwọn ra ara wọn pada". Ninu ọrọ yi, ẹ ri ẹkọ buburu ti Momodu fi kọ awọn Imale lati ma pa awọn enia ati lati ma sọ wọn di ẹlẹwọn, njẹ iru ẹkọ yi dun mọ Ọlọrun ninu? Njẹ iru ẹkọ buruku yi dara fun enia? Dajudaju gbogbo enia gbọdọ gba pe ọrọ ti Momodu sọ yi ko ba ifẹ Ọlọrun mu rara. Ẹkọ na kun fun iwa ipania ati inilara fun enia, lẹhinna o tun jẹ ọna lati fi gba owo lọwọ enia pẹlu inira.

Ṣugbọn Jesu Kristi kọ wa lẹkọ pe ki a maṣe ba ẹnikẹni ja rara, yala ọrẹ tabi ọta wa, O si tun kọ wa lati ma a ṣe ore fun awọn ọta wa. Matt. 5: 39-42; Luku 6: 27-35. Fun apẹrẹ ẹkọ rere na, lojọ ti awọn ọta wa mu Jesu lati kan An mọ agbelebu, ọkan ninu awọn ọmọẹhin Jesu fi ida ge ẹnikan leti sonu ninu awọn ota, ṣugbọn Jesu wipe, "Fi ida rẹ si ipo rẹ, nitoripe gbogbo awọn ti o mu ida ni yio ti ipa ida ṣegbe". Loju kanna ni Jesu si wo eti na san—Matt. 26: 51-54, Luk. 22: 47-51. Bakanna ni lojọ ti awọn ọmọ-ẹhin Jesu sọ fun U pe ki o pa awọn ota kan run, "Ṣugbọn Jesu yipada, o si ba wọn wi, o ni, ẹnyin ko mọ iru ẹmi ti mbẹ ninu nyin, nitori Ọmọ-enia ko wa lati pa ẹmi enia run bikoṣe lati gba a la".—Luk. 9: 54-56. Dajudaju Oluwa ati Olugbala rere ni Jesu Kristi iṣe.

KOI TI PARI.

*Ẹ ma a ka Iwe*
***IROHIN YORUBA***
*nigbugbogbo fun*
*irohin aladun*



Eyi ni aworan igbeyawo Ọgbẹni Ganiyu Ọlayiwọla Bello., ẹniti orukọ inagijẹ rẹ njẹ "Ọmọ-Agunbiade" ati 'Sammy Sparkle' ti iṣe ọkan ninu awọn ọga Oniwe Irohin "Daily Service" l'Eko pẹlu Omidan Nimọta Ọmọlara Onibudo nigbati nwọn ṣe igbeyawo ni Gbọngan Apejọ Ile-iwe Ansar-Ud-Deen, Alakoro l'Eko ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidilogbọn osu kejila ọdun ti o kọja yi. Ọkọ iyawo na jẹ ọmọ-bibi Alhaji Lasisi Bello, ọkan ninu awọn Aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko.




Ataburẹdi yi fi owo rẹ pamọ si

**BARCLAYS BANK D.C.O.**

Iwọ paapa le bẹrẹsi fi owo rẹ pamọ sibẹ lat'oni lọ.



**Gbigbona tabi Tutu**




**Gegebi IWỌ ba ti fẹ**

**GUINNESS**

**nfun ni ni ILERA ati AGBARA**

# IROHIN YORUBA

## Adajọ sọ Egungun kan si ẹwọn ọsẹ kan

ILESHA

NI ojo Aje ti ise ojo kedogun osu kejila odun ti o koja yi ni Oloye D. O. A. Oguntoye, Adajo Kotu Ibilẹ Ilesha sọ fun ọdaran egungun kan Idowu Lomolẹhin, ẹni ọdun mejilelogun pe, o jẹbi ẹsun ti nwọn mba a sejo si pe o ngna awọn enia ti ko ba ta a lọre ni inakuna nigbati o gbe egun, nitorina ki o fi ṣile marun tanran tabi ki o lọ si ẹwọn ọjọ meje (ọsẹ kan), o si tun kilọ fun un pe ki o ma a ṣọra nigbakugba ti o ba gbe egun.

# Ilana eto Iwe Orire idije bọlu-afẹsẹgba ilu oyinbo

**Lati ọwọ Arthur James**

ETO orire onilọpo-mẹta ti ọsẹ yi jẹ iranlọwọ fun awọn ti o ba fẹ fi ṣile mẹjọ (8s.) dokowo lori awọn iwe-eto-orire (coupons) ti o ni aala oni-kobọ kan fun ẹyọ kan, ni ọna ti o jẹ wipe o fi le ṣe iṣiro rẹ taara lori iwe-eto-orire laiwa iwe-iṣiro orire onila mẹrindinlọgọrun (96-line checking chart) mọ.

Iba ohun ti o ni lati ṣe niyi. Fa ila si ori aṣayan ti o ba buru julọ ninu ọwọ A. Fa ila si ori aṣayan ti o ba buru julọ ninu ọwọ B. Fa ila si ori aṣayan meji ti o ba buru julọ ninu ọwọ C.

Aṣayan mẹjọ pere ni yio wa a ṣẹku fun ọ gedegbe. Ro awọn ami (points) ti o ba ri ninu awọn aṣayan yi papọ, iye aropọ ami ti o ba ri nibẹ ni opin idahun ti wa a ri lẹsẹkese fun iye ami ti o ri gba ninu igbiyanju rẹ.

O ni lati kọ eto sinu iwe-eto-orire (coupon) gẹgebi a ti fihan ninu iwe-apẹrẹ (diagram), ṣugbọn ṣa, o ni lati, lo aṣayan mejila tirẹ.

Awọn Ẹgbẹ Idije Orire miran ngba owo idije ti o din to epini (half-penny) fun ila kan. Eto yi si dara pupọ fun iwe-eto-orire bẹ e, nitoripe ṣile mẹrin pere ni owo rẹ yio jẹ, ṣugbọn o ni lati ṣe atunṣe eto ilana rẹ lati ba idije elepinni mu.

8-MATCH TREBLE CHANCE

A
0)
0) Perm Any 2 from 4
0)
0)

B
0) In A, with any 3 from
0)
0) 4 in B, with any 2
0)

C from 4 in C.
0)
0) 4x4x6=96 lines at 1d.
0)
0) =8/- staked.

PICK OF SELECTIONS IN ORDER OF MERIT.

HOMES: Clyde, Hearts, Aberdeen, Swindon, Rangers, Walsall, Accrington, Shrewsbury, Aldershort.

DRAWS AND TREBLE CHANCE: Coventry, Luton, Brentford, Colchester, Wrexham Carlisle, Kilimarnock, Millwall, Tottenham.

AWAY: Bristol City, Hibernian, Celtic Reading, Partick, Bradford City, Cardiff, Birmingham.

| Forecast | F. A. CUP—THIRD ROUND | H. | D. | A. |
|---|---|---|---|---|
| | | 100—POINT FORM DIGEST | | |
| 1 | Accrington v Darlington | 60 | 19 | 21 |
| 1 | Aston V v Rotherham Utd | 69 | 18 | 13 |
| 2 | Barrow v Wolves | 21 | 20 | 59 |
| 1 | Blackburn R v Leyton C | 64 | 19 | 17 |
| X—1 | Brentford v Barnsley | 52 | 22 | 26 |
| 2—1 | Brighton v Bradford City | 46 | 21 | 33 |
| 1 | Bristol R v Charlton | 55 | 19 | 26 |
| 2 | Bury v Arsenal | 43 | 21 | 36 |
| X—1 | Colchester v Chesterfield | 53 | 22 | 25 |
| 2 | Derby C v Preston N. E. | 28 | 21 | 51 |
| 2 | Doncaster v Bristol City | 38 | 22 | 40 |
| 1 | Everton v Sunderland | 63 | 19 | 18 |
| 1 | Fulham v Peterborough | 73 | 16 | 11 |
| 1 | Grimsby v Man City | 58 | 19 | 23 |
| X—1 | Ipswich v Huddersfield | 56 | 21 | 23 |
| 1 | Leicester v Lincoln City | 66 | 17 | 17 |
| X—1 | Luton v Leeds Utd | 52 | 23 | 25 |
| 2—1 | Middlesbro v Birmingham C | 48 | 22 | 30 |
| 1 | Newcastle v Chelsea | 55 | 20 | 25 |
| 1 | Newport v Torquay Utd. | 57 | 20 | 23 |
| 2 | Norwich v Man. Utd | 22 | 18 | 60 |
| 2—1 | Plymouth v Cardiff City | 46 | 22 | 32 |
| 1 | Portsmouth v Swansea | 69 | 17 | 14 |
| 2 | Scunthorpe v Bolton | 32 | 24 | 44 |
| 1 | Sheffield Utd v Crystal P | 75 | 16 | 9 |
| 2—1 | Sheffield Wed v W. B. Albion | 47 | 22 | 31 |
| 2 | Southampton v Blackpool | 38 | 22 | 40 |
| 2 | Stockport v Burnley | 35 | 23 | 42 |
| 1 | Stoke C v Oldham Ath | 74 | 16 | 10 |
| 2 | Tooting & M v Nott'm F | 24 | 21 | 55 |
| X—2 | Tottenham v West Ham | 52 | 21 | 27 |
| 2 | Worcester C. v Liverpool | 37 | 22 | 41 |
| | FOOTBALL LEAGUE DIVISION III | | | |
| 1 | Hull v Southend | 57 | 21 | 22 |
| 2—1 | Notts C v Reading | 42 | 23 | 35 |
| 1 | Swindon v Bournemouth | 64 | 19 | 17 |
| X—1 | Wrexham v Q.P. Rangers | 55 | 22 | 23 |
| | DIVISION IV | | | |
| | Aldershot v Crewe | 58 | 21 | 21 |
| 1 | Carlisle v Watford | 53 | 22 | 25 |
| X—1 | Coventry v Port Vale | 49 | 23 | 28 |
| X—1 | Gillingham v Chester | 57 | 20 | 23 |
| 1 | Millwall v Northampton | 52 | 21 | 27 |
| X—2 | Shrewsbury v Bradford | 59 | 20 | 21 |
| 1 | Walsall v Workington | 60 | 21 | 19 |
| 1 | | | | |
| | SCOTTISH LEAGUE DIVISION I | | | |
| 1 | Aberdeen v Third Lanark | 65 | 18 | 17 |
| 1 | Clyde v Stirling A | 70 | 16 | 14 |
| 2—1 | Falkirk v Partick | 43 | 23 | 34 |
| 1 | Hearts v St. Mirren | 68 | 16 | 16 |
| X—1 | Kilmarnock v Dundee | 54 | 22 | 24 |
| 1 | Motherwell v Dunfermline | 54 | 20 | 26 |
| 2 | Q of South v Hibernian | 40 | 22 | 38 |
| 2 | Raith R v Celtic | 40 | 23 | 37 |
| 1 | Rangers v Airdrie | 63 | 18 | 19 |
| | DIVISION II | | | |
| 2—1 | Albion R v Stenhousemuir | 50 | 19 | 31 |
| 2—1 | Alloa v Hamilton | 50 | 21 | 29 |
| 2 | Berwick R v Arbroath | 35 | 21 | 44 |
| 2—1 | Cowdenbeath v Ayr Utd. | 46 | 20 | 34 |
| 2 | Dundee Utd. v Dumbarton | 39 | 19 | 41 |
| 1 | Forfar v East Stirling | 69 | 17 | 14 |
| 2—1 | Morton v East Fife | 47 | 21 | 32 |
| 1 | Queens Park v St Johnstone | 55 | 20 | 25 |
| 2 | Stenraer v Brechin City | 44 | 20 | 36 |




Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 3/7 Apongbon Street Lagos (Editorial and Advert offices) Telephone 23675. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan: Eko—sile mejo ati kobo mejo (8s 8d.) Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun—sile metala (13s.). Oloto E. M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street Lagos.